# AWỌN ASỌTẸLẸ NIPA MESSIA

## Orin Dafidi 2:1-12; 22:1, 18; 45:1-17; 68:16-19; 69:20, 21; 110:1-7; 118:21-24; 132:11

## ẸKỌ 470 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitori eyi li Ọmọ Ọlọrun ṣe farahàn, ki o le pa iṣẹ Èṣu run" (1 Johannu 3:8).**

### Ifẹ Ọlọrun

Ninu Johannu 3:16 a sọ fun wa pe: "Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun."

Ko le ṣe i ṣe fun wa lati mọ ijinlẹ ifẹ Ọlọrun. Lati ro pe yoo rán Jesu, Ọmọ Rẹ kan ṣoṣo, si ayé ẹ̀ṣẹ yii gẹgẹ bi Ọmọ-ọwọ ni Bẹtlẹhẹmu! A bi I lati inu Maria Wundia ki a le tọ Ọ dagba ni ibi ti o rẹlẹ, lẹyin naa ki O le fi ẹmi Rẹ lelẹ lori agbelebu nitori ifẹ Ọlọrun, Baba Rẹ si wa.

### Ileri Ọlọrun

Ninu Ọgba Edẹni ni Ọlọrun ti kọ́ sọ asọtẹlẹ fun eniyan nipa "Olugbala" ti n bọ̀. Bi o tilẹ jẹ pe Adamu ati Efa ti dẹṣẹ. Ọlọrun ki yoo jẹ ki wọn lọ si ayeraye lai si atunṣe fun ẹ̀ṣẹ wọn. Kristi ni "Ọdọ-Agutan ti a ti pa lati ipilẹṣẹ aiye" (Ifihan 13:8).

Nigba pupọ ninu ọpọ ọgọrun ọdun ti Majẹmu Laelae ni Ọlọrun ti sọ ileri Olurapada ti n bọ̀ di ọ̀tun. Ofin ti Mose fun ni, ati awọn ilana rẹ, tọka si Olugbala araye ti yoo ta Ẹ̀jẹ Rẹ silẹ ni ọjọ kan fun idariji ẹ̀ṣẹ gbogbo ayé.

### Suuru Ọlọrun fun Awọn Onilọra Eniyan

Ọlọrun mọ pe eniyan lọra lati kọ́ ẹkọ, wọn si maa n yara lati ṣaigbọran si aṣẹ Rẹ̀. Ninu suuru ati ifẹ Rẹ, Ọlọrun fi ọpọlọpọ ọdun ati oniruuru ọna mura awọn eniyan Rẹ silẹ fun wiwa Ọmọ Rẹ sinu ayé yii.

A sọ fun wọn lati ọwọ awọn wolii pe, a o bí Ọmọ Ọlọrun lati inu wundia. A si sọ orukọ ilu ti a o gbé bi I paapaa fun wọn. A jẹ ki o di mimọ̀ pe Ẹmi Ọlọrun yoo ba le E. A o si maa pe orukọ Rẹ ni Iyanu, Oludamọran, Baba Ayeraye, Ọmọ-Alade Alaafia.

Awọn wolii pẹlu sọ asọtẹlẹ nipa ijiya Rẹ, ikú Rẹ, isinku ati ajinde Rẹ. Wọn sọ nipa Ẹ̀jẹ etutu Rẹ ati ìnà Rẹ fun imularada wa. Kò ti i si ẹlomiran ti a bi ti a sọ asọtẹlẹ nnkan pupọ bayii nipa rẹ̀.

### Ibi Olurapada

Ni oru ọjọ kan, ni nnkan bi ẹgbaa ọdun sẹyin, angẹli kan yọ si awọn oluṣọ-agutan diẹ kan lẹgbẹ oke kan ni Bẹtlẹhẹmu lati kede ibi Jesu. "Ọpọlọpọ ogun ọrun si yọ si angẹli na li ojijì, nwọn nyin Ọlọrun, wipe, Ogo ni fun Ọlọrun loke ọrun, ati li aiye alafia, ifẹ inu rere si enia" (Luku 2:13, 14).

Awọn oluṣọ-agutan naa tara ṣaṣa lọ si ibujẹ ẹran, wọn si ri Ọmọ-ọwọ naa ti i ṣe Kristi. Wọn pada si ibi agbo ẹran wọn pẹlu ayọ nlá nlà, wọn si n royin fun awọn ẹlomiran nipa ohun iyanu nla naa ti o ti ṣẹlẹ.

Nigba ti Jesu di ọmọ ogoji ọjọ, a gbe E lọ sinu Tẹmpili gẹgẹ bi Ofin (Lefitiku 12:3, 4). Nigba ti O wà nibẹ, awọn oloootọ, ọmọ Ọlọrun meji, Simeoni ati Anna ri I. Ẹmi Ọlọrun fi hàn wọn pe eyi ni Olurapada naa. Ifẹ ti o leke ọkàn wọn ni gbogbo ọjọ ayé wọn lati ri Messia ni a mú ṣẹ. Awọn pẹlu sọ asọtẹlẹ nipa ohun ti yoo ṣẹlẹ si I ni ọjọ iwaju (Luku 2:25-38).

### Ayọ̀ Dapọ mọ́ Ibanujẹ

Pẹlu ireti awọn ileri nipa Olurapada ti n bọ̀ ni asọtẹlẹ ti o ba ni ninu jẹ nipa kikọ Ọ silẹ, ijiya ati iku Rẹ. "Awọn ọba aiye kẹsẹ jọ, ati awọn ijoye ngbimọ pọ̀ si OLUWA ati si Ẹni-Ororo rẹ pe, Ẹ jẹ ki a fa ìde wọn já, ki a si mu okùn wọn kuro li ọdọ wa" (Orin Dafidi 2:2, 3). "Ẹgan ti bà mi ni inu jẹ; emi si kún fun ikãnu: emi si woye fun ẹniti yio ṣãnu fun mi, ṣugbọn kò si; ati fun awọn olutunu, emi kò si ri ẹnikan. Nwọn fi orõro fun mi pẹlu li ohun jijẹ mi; ati li ongbẹ mi nwọn fun mi li ọti kikan ni mimu" (Orin Dafidi 69:20, 21).

A gbọdọ kún fun ọpẹ si Olugbala ti O fi tifẹtifẹ wá, bi o tilẹ jẹ pe O ti mọ̀ pe ọna palapala ti Oun yoo rin yoo mu Oun lọ si ori oke Kalfari.

### Iṣẹgun nipa Ikú

Hẹrọdu wá ọna lati pa Jesu nigba ti O wà ni Ọmọ-ọwọ; awọn miiran gbiyanju lati taari Rẹ lati ori oke lati pa A nigba ti iwaasu Rẹ dá wọn lẹbi. "O tọ̀ awọn tirẹ wá, awọn ará tirẹ kò si gbà a" (Johannu 1:11). Nikẹyin awọn alakoso Ju bori ni didá A lẹbi ikú. Wọn kigbe pe, "Kàn a mọ agbelebu! Kàn a mọ agbelebu!" Wọn wi

pe “Ki ẹjẹ rẹ̀ wà li ori wa, ati li ori awọn ọmọ wa” (Matteu 27:25). Jesu kigbe lori Agbelebu pe, “Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ?” (Orin Dafidi 22:1).

Ikú Jesu ki iṣe opin Rẹ̀ gẹgẹ bi ayé le ti fẹ gbagbọ̀ ki o si maa kọ̀ ni bẹẹ. Ninu ikú Rẹ̀, Oun jẹ́ Ọdọ-Agutan ti kò ni abukù, ti kò si ni abawọn! O mu gbogbo apẹẹrẹ awọn ọdọ-agutan ti Majẹmu Laelae ṣẹ, awọn ti a fi rubọ labẹ Ofin lati ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ. O ta Ẹ̀jẹ Rẹ̀ silẹ fun imukuro ẹ̀ṣẹ wa.

Ṣugbọn ikú kò lagbara lori Olugbala wa lọ titi. Ni ọjọ kẹta, O jinde pẹlu iṣẹgun lori ikú, ọrun-apaadi ati iboji. Lẹẹkan si i, angẹli tun kede pe “Ēṣe ti ẹnyin fi nwá alãye lãrin awọn okú? Ko si nihinyi, ṣugbọn o jinde” (Luku 24:5, 6).

Ìbí irẹlẹ, ikú itiju, ajinde ologo! Ohun gbogbo ti O ti ṣe jẹ igbọran si ifẹ Baba Rẹ̀. Ọlọrun sọ nipa Rẹ̀ pe: “Eyi ni ayanfẹ ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi” (Matteu 3:17).

**Tun n Pada Bọ̀**

Pẹlu awọn asọtẹlẹ ìbí, igbesi-ayé, ikú ati ajinde Jesu, eyi ti a saba maa n pe nigbakuugba ni wiwa Rẹ̀ tabi bibọ Rẹ̀ lẹẹkinni, ni a ri awọn ileri iyanu nipa ipadabọ Jesu lẹẹkeji sinu ayé. Ọpọ ileri ni o wà ni ti akoko ti a o fi gbogbo awọn ọta sabẹ ẹsẹ Rẹ̀.

Awọn ileri bibọ̀ Jesu lẹẹkeji ati ọjọ ti ohun gbogbo yoo wà labẹ Rẹ̀ kò mu ayọ̀ tabi ireti wá fun ẹlẹṣẹ ati alaiwa-bi-Ọlọrun.

Satani ati gbogbo awọn ti wọn ti sin in yoo ti lo igba ti wọn kọja nigba naa. “Ẹniti o joko li ọrun yio rẹrin: Oluwa yio yọ ṣùti si wọn. Nigbana ni yio sọ̀rọ si wọn ni ibinu rẹ, yio si yọ wọn lẹnu ninu ibinujẹ rẹ̀ kikan. Ṣugbọn mo ti fi Ọba mi jẹ lori Sioni, òke mimọ́ mi … Bère lọwọ mi, emi o si fi awọn orilẹ-ède fun ọ ni ini rẹ, ati iha opin ilẹ li ọrọ̀-ilẹ rẹ. Ọpa irin ni iwọ o fi fọ́ wọn; iwọ o si rún wọn wom-wom, bi ohun-èlo amọ̀” (Orin Dafidi 2:4-9).

Dajudaju gẹgẹ bi a ti fi tiyanu-tiyanu mu awọn asọtẹlẹ wiwa Jesu si ayé lẹẹkinni ṣẹ, bakan naa ni awọn asọtẹlẹ wọnni nipa pipadabọ Rẹ̀ lẹẹkeji lati gbé Ijọba Rẹ̀ ti kò nipẹkun kalẹ, yoo ṣẹ. “Ọlọrun, lai ati lailai ni itẹ́ rẹ: ọpá-alade ijọba rẹ ọpá-alade otitọ ni. Iwọ fẹ ododo, iwọ korira iwa-buburu: nitorina li Ọlọrun, Ọlọrun rẹ ṣe fi àmi ororo ayọ̀ yà ọ ṣolori awọn ọ̀gba rẹ” (Orin Dafidi 45:6, 7). “Ijọba aiye di ti Oluwa wa, ati ti Kristi rẹ̀; on o si jọba lai ati lailai” (Ifihan 11:15).

**Ẹbun Ọlọrun**

Nitori ifẹ nla Ọlọrun, Ọlọrun fun wa ni Ọmọ bibi Rẹ̀ kan ṣoṣo. Ọmọ Ọlọrun, Ẹbun Ọlọrun, ṣugbọn awọn eniyan diẹ ni o mọ riri Rẹ̀. A gbọdọ fi ọkàn ọpẹ gba ẹbun ti a fun ni ki o baa le mu ayọ̀ ti o yẹ ba ẹni ti o gba a ati ẹni ti o fi fun ni bakan naa.

Boya irubọ nla ti Ọlọrun ṣe nipa rirán Ọmọ Rẹ̀ wá si ayé le jẹ ohun iyanu pupọ fun ọ. Iru iha wo ni o kọ si ẹbun Ọlọrun naa? Njẹ o mọ pe Jesu jẹ ẹbun fun iwọ tikara rẹ gan an, tabi o kò bikita fun ẹbun naa, o si kuna lati ri aile-fẹnusọ iyebiye Rẹ̀? A ko le fi awọn ohun ayé yii wé “pearli olowo iyebiye.” “Ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa” (Romu 6:23).

## AWỌN IBEERE

1 Nigba wo ni a kọ́ ṣe ileri Olugbala fun ni?
2 Nigba wo ni Ọlọrun gbé ilana igbala Rẹ̀ kalẹ?
3 Bawo ni Ofin ṣe tọka si Jesu?
4 Sọ asọtẹlẹ meji ninu Majẹmu Laelae nipa ibi Jesu.
5 Awọn ọrọ wo ni a ri ninu Orin Dafidi ti Kristi sọ lori agbelebu?
6 Asọtẹlẹ wo ni a sọ nipa aṣọ Kristi?
7 Ki ni ṣe ti ikú Kristi ki i ṣe opin Rẹ̀?
8 Ki ni ṣe ti a maa n tọka si Kristi gẹgẹ bi ọdọ-agutan?
9 Awọn wo ni ẹni kin-in-ni ti o kọ́ gba ihin ibi Jesu?